# ALAYE LORI

## Ipo Ti Awon Ohun Ogbin Imo-Ero Ti O Ye Fun Tita Wa Lagbaye:
## Ti Odun 2012 Onkowe Ni Clive James, Ti Oje Oludasile Ati Alaga Ajo ISAAA
## A ko eyi fun billion kan alaini pelu awon ti ebi npa, lati le doola la emi won

---

**Saare Ohun Ogbin Imo-Ero ti gbe peeli si lona ti o wuyare ni ilopo ogoorun lati odun 1996 pelu million kan abo-le-igba(1.7million) si aadosan million saare(170million) ni odun 2012.**

Akosile fihan pe aadosan million-o-le oodunrun(170.3million) saare oko ni a fi sogbin imo-ero yii lagbaye ni odun 2012, ti o tumosi ida mefa ninu ogoorun lodun(6%), ti o si ju ti odun 2011 ti o je ogoosan million(160million) saare lo pelu million mewa-o-le oodunrun(10.3million) saare.

Odun 2012 ni a ni akosile igbepeeli saare ohun ogbin imo-ero ti o wuyare ni ilopo ogoorun, lati million kan abo-lerugba(1.7million) ni odun 1996 si aadosan millionu (170million)saare ni 2012, eyi lo mu ki ona ogbin Bt di itewogba ninu itan - kini idire –won ni ere to po jojo.

Ogunlogo awon agbe, ni orileede ti o to ogbon lagbaye lo se ipinu ti o ju ogoorun million lati sogbin sori saare ti o ju billion kan abo(1.5billion)saare lo laarin odun 1996 si 2012, ni eyi to ju ile orileede US tabi China lo ni ida aadota ninu ogoorun(50%): ti o sapere ifokanbale ti ogunlogo awon agbe ti won ti foju wina eto ogbin ohun lo jewo wipe eto ogbin Bt maa ntojo, atipe a maa sanfaani fun oro aje ati ayika ibi ti a ti gbin.

Awon orileede tuntun meji bi Sudan(to sogbin owu Bt) ati Cuba(oka Bt) fun igba akoko ni odun 2012. Nitori oja Anamo “Amflora” ti ko ya ni ko je ki orileede Germany ati Sweden sogbin re: bakanna orileede Poland dawo gbigbin Agbado Bt duro latari pe won ko le sakoso re.

Ninu awon orileede mejidinlogbon to sogbin ni liana igbalode yi ni odun 2012, ogun ni o sese ngoke agba, ti mejo je orileede ti nileese nlanla; a le fi eyi we mokandinlogun orileede ti o sese ngoke agba ati mewa ti o nileese nlanla ni odun 2011.

Million metadinlogun-le oodunrun (17.3million) awon agbe ti o fi egbeta(0.6million) ju ti odun 2011 lo ni o fi imo-ero Bt sogbin ni odun 2012, awon ti o ju ida aadorun ninu ogoorun(90%) tabi million meedogun ni o je agbe ti osi nta ni awon orileede ti o sese ndagba. Awon agbe yii naa ni kii fe fi oju wina lori eto ogbin, atipe, ni odun 2012, akosile fihan pe million meje-o-le-igba(7.2million) agbe kereje ni orileede China ati iye million kannaa ni India ni won dibo yan lati sogbin Owu Bt sori saare oko ti o to millionu meedogun, nitori awon anfaani ti o ro mo.

Fun igba akoko, awon orileede tondagba peleke si ju awon ti o nileese nlanla lo ninu eto imo-ero pelu ida meji-le-laadota si ida mejidinlaadota ninu ogoorun(52% - 48%) ni odun2012. Ni odun 2012 yii kanna, eto ogbin Bt goke sii ni ilopo meta ati ilopo marun ju ti awon orileede to se ndagba ni iwon bii ida mokanla ninu ogoorun(11%) tabi million mejo-o le eedegberin (8.7million)saare, pelu ida meta ninu ogoorun tabi millionu kan-o-le egbeta (1.6million)saare ti o je ti orileede ti o nileese nlanla.

Sisogbin ni ona ti ko bojumu se Pataki lati gbe yewo, orieede metala lo sogbin imo-ero ni ona mereyiri ni odun 2012, eyi to wuni lori julo nipe mewa ninu metala ni o je awon orileede to sese ndagba – (43.7million) saare tabi eyi ti o ju ida merin aadosan million (170million)saare oko ti a gbin ni ona ti ko wuyi yii ni odun 2012.

Fun odun merin leralera ni orileede Brazil fi se ogbin imo-ero ju awon orileede to ku lagbaye pelu akosile to pegede ni iwon million mefa-o-le loodunrun (6.3million)saare oko ti o fi ida mokanlelogun ninu ogoorun ju ti odun 2011 lo, eyi ti o nsumo million merindinlogoji-o-leegbeta (36.6million)saare oko.

Orileede US ni o si n gbegba oroke pelu million mokandinlaadorin abo(69.5million) saare, pelu gbingbin orisirisi ohun ogbin nib ii ida aadorun ninu ogoorun. Oda ojo to sele lorileede US lo mu ki won padanu agbado ni iwon ida mokanlelogun ninu ogoorun ti ti soyabean je ida mejila ninu ogoorun. Orileede Canada ni akosile million mejo-o-le irinwo saare oko Canola ti o sapere ida bii mejidinlogoorun ninu ogoorun(97.5%) ti o je itewogba.

Akosile fihan pe million mewa-o-le egberin (10.8million)saare ni orileede India fi sogbin Owu Bt pelu itewogba bii ida metalelaadorin ninu ogoorun, nigbati million meje-o-le igba (7.2million)awon agbe kereje ti ko rowo sogbin lorileedee China gbin owu Bt yii kanna sori saare oko ti o to million merin pelu itewogba bii ida ogoorin ninu ogoorun si n sogbin idaji saare fun agbe kan. Orileede India pa owo ti o to billionu mejila-o-le egbeta dollar(US$12.6billion) nipa gbingbin Owu Bt ni odun 2002 si 2011 ati billion meta-o-le igba dollar(US$3.2billion) ni odun 2011 nikan.

Orileede Africa pelu South Africa ntesiwaju ninu eto ogbin yii pelu idaji millionu saare oko o le die ti o sunmo millionu meji-o-le eedegberun (2.9million)saare; orileede Sudan darapo mo South Africa, Burkina Faso ati Egypt, eyi ti o mu ki akojopo Adulawo to nse eto ogbin imo-ero je merin.

Orileede Eu marun lo gbin Agbado Bt sori saare oko ti o to egberun lona aadoje(129,071), ti ofi ida metala ninu ogoorun ju ti 2011 lo. Bakanaa orileede Spainsogbin agbado Bt yii ju EU lo pelu saare oko to sunmo egberun lona ogoofa(116,307) ti o fi ida ogun ninu ogoorun ju ti 2011 lo.

Laarin odun 1996 si 2011, ogbin imo-ero yii sokunfa opo ounje ati ayipada oju ojo nipa: mimu ki ohnu ogbin po si ni iye owo to to billionu mejidinlogorun-o-le igba dollar(US$98.2billion), o si nseto ayika to dara nipa didin ilo oogun apa kokoro ku ni iwon aadorin-lenirinwo kilo(473kg): ni odun2011 nikan o din afefe oloro CO2 ku ni iwon billionu metalelogun kilo ti o dogba pelu kiko millionu mewa-le igba moto kuro loju popo; didaabobo ohun abemi ti o wa layika wa nipa didaabobo saare ile to to millionu mejo-o-le logoorun ati eedegberin; ati didin osi ku nipa reran awon agbe kereje to ju millionu meedogun lo lowo ati awon ebi won ti gbogbo re ju aadota millionu eniyan lo; ti won wa lati iha ibi ti awon eniyan to tosi ju lagbaye. Eto ogbin imo-ero yii se Pataki ni tooto, sugbon kii se ona abayo si sise agbe lona ti o dara ju akore-dare-si ati fifun ohun ogbin lagbara eyi to pon dandan fun ohun ogbin Bt bi o se pon dandan fun awon ohun ogbin miran.

Aini isakoso ti o niise pelu imojinle Sayensi, to gun rege ti ko nani lowo tabi gba akoko eni yoo maa je idena fun itewogba ilana eto ogbin yii. Isakoso to wuyi, ti a fi taratara se sugbon ti ko mu iyonu lowo ni awon orileede kekeeke, ti osi nta ti o sese ndagba nilo.

Irugbin Bt lagbaye to billionu meedogun dollar(US$15billion) ni odun 2012.
Ojo ola – pelu awon ere ti anri lodun, a le sope ireti wa fun ojo ola eto yii yoo dara pelu bi awon eniyan se ntewogba, paapajulo, awon ohun ogbin ti o se Pataki ti won nta ni awon orileede ti o se ndagba ati onileese nlanla.

Ajo ti ko duro de ere, ti awon araalu ati awon aladani n fowo ran lowo ni ISAAA je.

Eekan pere ni a ka gbogbo awon saare oko ti a fi sogbin imo-ero(biotech) ti a ko sile ninu awon iwe ISAAA, laifi ti iye adamo/akanse ti awon ohun ogbin naa ni se. Ekunrere alaye wa ni ISAAA Brief 44 **"Ipo Ti Awon Ohun Ogbin Imo-Ero Ti O Wa Fun Tita Wa Lagbaye: Ti Odun 2012,** ti Clive James ko. Fun ibeere e wo ori ero ayelujara ti http://www.isaaa.org tabi ki o kan si ISAAA AfriCenter pelu nomba yii +254 20 4223618, tabi africenter@isaaa.org.